ADURA FUN ỌSẸ YI

Jẹki alẹ san wa ju owurọ lọBaba rere

# IRAWỌ ★ OBOKUN

OWE ỌSẸ YI

Kise pe anfani fun ẹtu lasan oni ori eniti o ba ẹtu jọ

Vol 3 No. 136 ILESHA. MONDAY MAY 2 1955. IYE OWO: TỌRỌ

# IJỌ C. M. S. ILE IJESA SE IRANTI OLOGBE ALUFA S. O. MAFE

## IDAHUN SI ỌRỌ AKINDELE OJO

(Lati ọwọ J. O. Awosan)

Gẹgẹbi ọrọ ti Akindele Ojo kọ sinu Irawọ Obokun ti ọjọ kẹdọgbọn osu yi 25/4/55 mo fẹ ṣe alaye fun gbogbo enia wipe otitọ kan kosi ninu ọrọ rẹ na. Nigbati Ọgbẹni Lalẹyẹ fi isẹ Ọ otu silẹ ni Akindele Ojo ti nṣe isẹ yi ti osi nko orisirisi ọrọ ti o fẹ silẹ nigbati awọn alakoso ibi isẹ yi ri irubọ ọpọ ọrọ tiko bojuma ti Akindele Ojo nko jade, to le mu ijọngbọn dani ni wọn ba kọ we si ni ọjọ kejilelogun osu kọkanla ọdun to kọja 22/11/54 wipe gbogbo iwe ti yio ba tẹ jade ninu Irawọ Obokun gbọdọ de Office B 110 Okeṣa fun ayẹwo, sugbọn lati igbana Akindele kọ lati ko awọn iwe na wa to bẹ ti o fi kọ iwe si awọn alakoso ni ọjọ kẹrinlelogun (24/11/54) na pe on kole fi ara mọ iru aba bayi awọn

(Bẹrẹ ni oju iwe 7)



OLOGBE ARCHDEACON S. O MAFE

On ni ẹniti gbogbo ijọ C. M. S ti ile Ijesha ṣe akanse isin kan pataki ti iranti rẹ ni ọjọ isimi tise ọjọ kẹrulelogun osu April.

## ABUDU SARUMI JẸ OYE ARAPATẸ

Ni ọjọ alamisi ti se ọjọ kejidinlọgbọn 28:4:55 ni a fi Alfa Abudu Sarumi jẹ Oye Arapate Ilesa gẹgẹbi eto ijoye ibilẹ lati ọwọ awọn Ijoye. Ki o to to agogo marun irọlẹ ni ẹsẹ awọn enia pataki pataki ninu ẹoi, ọrẹ, ana, ati ojulumọ alfa yi ti pesẹ siwaju Gbọngan Obokungbusi fun ti Oye na.

Bi o ti di agogo marun ni Oloye titun yi de si afin Ọba Ọwa Ajimọkọ. Lẹhin ti a ti se etutu ni aba mu wa siwaju lati fi han Ọba pẹlu awọn ijoye ti o tẹle wọn si dọbalẹ niwaju Ọba si se adura fun.

Lẹhin awọn eto wọnyi ni aba sọ wipe Arapatẹ ma huye ajẹgbo ajẹtọ awọn onilu Ọba si tẹle pẹlu ogunlọgọ awọn enia.

## Anglican Girls' Secondary School Ilesha.

Entrance Examination for Class One Secondary Grammar, January, 1956. Saturday, June 4, 1955

Subjects :- English and Arithmetic Pupils eligible to sit for the First School Leaving Certificate in 1955, and Pupils who passed it in 1954 and are not in any Secondary Mordern, may apply. Application for entrance forms to be obtained from the Principal through Head masters of your School. Entrance fee 3s. to be sent before forms can be sent.

Centres:- Ilesha, Ibadan, Ondo, Ijebu-Ode, and Abeokuta Girls' Schools.

Closing date:- May 21st for Ilesha and Districts only because of the hol days.

Principal.

## IFILO PATAKI

Awọn Alakoso ile iṣe Ijesha Press Ltd. ni ki aṣe ifilọ yi fun gbogbo awọn ẹniti wọn da owo sinu iṣẹ yi yala ni ilu Ilesha tabi Idalẹ pe afẹ ki onikaluku fi akọtan orukọ rẹ ransẹ si Office Ijesha Press Ltd ni B,110 Okesha tabi P.O. Box 23 Ilesha.

Fun apẹrẹ ẹniti oba njẹ J. O. Aina afẹ ki o sọ orukọ ti J. O. duro fun, ki aba le fi akọtan orukọ yi sinu iwe ti ao fi ransẹ si onikaluku laipẹ yi.

Alabojuto

## IJỌ C.M.S. ILE IJẸṢA ṢE ISIN IRANTI ARCHDEACON S. O. MAFẸ

(Lati ọwọ J. O. Awosan)

Lati ọjọ die sẹhin ni gbogbo awọn enia Ijọ ti C. M. S. ti ilẹ Ijẹṣa ti nṣe imurasilẹ fun isin iranti pataki ti nwọn fẹ ṣe fun ologbe Archdeacon S. O. Mafẹ, a si ti fi iwe ipe ransẹ si ọpọlọpọ awọn enia pataki ni ilu yi ati idalẹ.

Ni ọjọ isimi tise ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi (24 : 4 : 55) ni gbogbo awọn enia Ijọ C.M.S. Ilesa a'i agbegbe pejọ ni ile Ọlọrun Johanu Mimọ Ilọrọ fun isin akanṣe pataki na. Ki o to di agogo merin ti isin na yio bẹrẹ ni Ile Ọlọrun na ti kun pupọ ti ogunlọgọ awọn ẹnia fi duro si ejude.

Nigbati o di dede agogo mẹrin ọsan ọjọ na ni isin yi ba bẹrẹ Eni-ọwọ Alufa M. A. Orege ti Ibokun lo fi orin 217 bẹrẹ, bi a si ti nkọ orin yi ni awọn akọrin lokunrin ati lobirin ba to lẹsẹsẹ pẹlu ogunlọgọ awọn Alufa, akawe mimọ ati Biṣọbu gba ẹnu ona isalẹ wọ inu Ile Ọlọrun, ra, bi a ti nkọ orin yi ni Eni-ọwọ Alufa yi nka iwe ti isinku.

Lẹhin ti a kọ orin yi tan ni Eni-ọwọ Alufa J. D. Osomọ ti Ijọ Isọna ba ka iwe ijiwọ ẹsẹ Eni-ọwọ Alufa I. E. Fajẹtitokun ti Ipetiado lo pe Psalm 90 eyiti gbogbo Ijọ si kọ ni orin.

Lẹhin eyi ni Ẹni-ọwọ Alufa D. A. Yoloye ba ka ẹkọ fun isin na lati inu iwe Ifihan ori 7 ẹsẹ 9 de opin, bi ati ka iwe yi tan ni Ẹni-ọwọ Alufa Okunmuyide ba pe orin 358 bi a si ti nkọ orin na tan ni Ẹni-ọwọ Alufa J. O. Daramọla ti Ijọ Omọfẹ ba gbadura fun iranti ologbe na.

Bi ati gba adura yi tan ni Ẹni-ọwọ Alufa J. D. Ajamọbi ti Ifẹwara ba pe orin 417. Ni kete ti a kọ orin yi tan ni Ẹni-ọwọ Alufa D. A. Ọlaitan ba gun ori aga iwasu osi yan iwe Iṣe Aposteli ori kẹtala ẹsẹ kẹrindinlogoji (Act 13-36) o si sọrọ pupọ nipa igbesi aiye ologbe Archdeacon S. O. Mafẹ pe o jẹ oniwa tutu enia o si jẹ o si jẹ olohun iyọ tobẹ ti ọpọ enia fẹ lati ma gbọ wasu rẹ yala ni C. M. S. tabi Ijọ Eleto Methodist kakiri ilu gbogbo O sọrọ nipa bi o ti mọ igbesi aiye rẹ si pe o wa ni Ile-Ẹkọ ti a ti nkọni fun iṣẹ alufa ni Ọyọ ni ọdun 1906 o si fi ibẹ silẹ ni ọdun 1911 labẹ abojuto Ẹni-Ọwọ Bishop S, C. Phillips. O bẹrẹ iṣẹ Katikisi ni ọdun 1916 o tun pada si Ile-Ẹkọ Ọyọ ni 1920 a fi jẹ oye alufa kekere ni ọdun 1923 o si di alufa agba ni ọdun 1927 o si siṣẹ ni awọn ọpọ ilu bi Isara, atun gbe lọ si

Bẹrẹ ni oju iwe 7

## ỌGBẸNI AGBỌLA MAKINWA GBE IYAWO

(Lati Ọwọ J. O. Awosan)

Ni ọjọ isinmi tise ọjọ kẹtadinlogun osu to koja ni Ọgbẹni Agbọla Makinwa tiṣe ọkan ninu awọn onisowo pataki ni Ilọrin gbe Omidan Iyabọ ti odo Agbede Ilesa ni Iyawo.

Ni dede agogo mejila ọsan ọjọ yi ni awọn Orẹ, Ebi, Iyawo ati ojulumo ọkọ Iyawo yi ti pese si ile rẹ ni adugbo Anaye lati ba lọ si ile Baba Iyawo rẹ ni adugbo Odo Agbede. Ki awọn enia wọnyi to de ile baba ọmọ ni wọn ti pese ipanu ati onjẹ orisirisi silẹ pẹlu ẹmu ati ọti bia.

Bi Ọkọ Iyawo ti wọle pẹlu awọn enia rẹ ni aba mu wọn lọ si ibiti ati pese aye sile de wọn bi onikaluku ti njoko ni aba ngbe awọn onjẹ aladun silẹ niwaju wọn. Bi wọn ti jẹun tan ni aba gbe ẹmu to ṣana jade ati ọpọ igo Bia ti ako le ka iye rẹ onikaluku awọn enia ti o wa nibẹ lo si gb dun ara rẹ dada.

Inawo ọjọ na pọ pupọ tobẹ ti awọn ti o wa nibẹ fi rse adura fun Baba, Iya, Ọkọ ati awọn ebi wọn pe Ọlọrun yio ṣe iyawo na ni abiyamọ. Awọn enia Ọkọ ni ranṣẹ si Iyawo lati wa ni ki wọn lẹsẹkanna ni Iyawo pẹlu awọn Ọrẹ rẹ ba wa pẹlu ẹrin lati ki wọn. Awọn enia ti o wa ta Iyawo na lọrẹ owo.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa nibi Iyawo na ni Ọgbẹni Joseph Aloya, James Coker, S. A Olowokere, G. L. Ogini, J. E. Ayẹni, S. O. Agunda, J. O. Awosan, Agbọla Makinwa, tiṣe ọkọ Iyawo Tunji Anjorin, Akindele Makinwa, Bọla Makinwa, Omihunmi Makinwa, Bọsede Bọlarin Alice Coker, Florence Coker, ati ọpọlọpọ enia ti ako le daruko tan.

Akọle Olotu Aki Ọgbẹni Agbọla Makinwa Ọkọ Iyawo Olọwọato elese osun Abe Adeniyi baba Iyawo Jẹbẹ iya Iyawo, ati Arsenia Ogundipẹ ati awọn ebi Ọkọ Iyawo pe wọn ku inawo Ọlọrun yio ṣe iyawo na ni abiyamọ. Ki Ọlọrun fi ohun ayọ ati rere bayi kari gbogbo wa o.



KANSẸLỌ E O ORIOWO

On jẹ aṣoju Ijọ Johanu Mimọ Ilọrọ nibiti ati se akanse isin pataki kan ni iranti Ologbe Archdeacon S O Mafẹ tise Alula Ijọ na.



OLOYE AGUNLEJIKA KEJI LỌJA OKEBODE

On ni enit a fi ṣe alaga ni ọjọ ti a se ipade Ijọba titun kiri ni Ibi Okebode o si ba gbogbo awọn enia ti o wa sọ ọrọ isiri papọ lati inu Bibeli Mimọ.

## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

Afẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede. AKỌWE

## ADENIRAN FOWOWE WA SE OKU BABA RẸ

Ọgbẹni Adeniran Fowowe Ọga ile isẹ itẹwe ti Fowowẹnu, Auchi ati Ẹdaolulu Irrua ti de si ilu lati ọjọ alamisi 28 4 55 eyiti ise ọjọ kejidinlogbọn osu yi fun isinku Baba rẹ, Ọgbẹni Abraham Fowowẹ Alaṣọniwọle o osun ninu Olu wa ni ọjọ kẹtadinlogbọn osu yi.

**WANTED URGENTLY**

Two Journeymen Printers to manage a press each

Apply in person

Adeniran Fowowẹ,

E 200 Oke Ẹshọ,

ILESHA:

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ oruko ti on papa njẹ pẹlu adugbo rẹ. Toripe ọpo iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ko ni tẹ jade.

ALABOJUTO

### IDAHUN SI ỌRỌ AKINDELE OJO
(Bẹrẹ ai oju iwe I)

alakoso ibi isẹ yi tun kọwe si ni 3/1/55 pe igberaga lo jasi ti Akindele Ojo ni lati ma pasẹ tabi sọrọ alebu si wọn atipe on ti wọn sọfun ni ko gba sibẹsibẹ ko fi ara mọ. Ninu gbogbo awọn iwe rẹ ti o jade ni 25/1/55 Lori ọrọ Oye Arapatẹ, Ẹgbẹ Ọdọ Action Group ati Isẹ ẹranko nişe Ọpẹ emi kori ẹda iwe na rara Akindele Ojo lo nkọ lai fi han mi rara ẹda iwe na si wa ni ile rẹ. Lati tun ja irọ Akindele Ojo ti ẹba ka iwe ti o ba awọn idile Arapatẹ kọ, o kọ sidi iwe na wipe Akọle Olotu on lo kọ eleyi fun ara rẹ bẹni ọpọ iwe lo ti nkọ fun idile Ojoye yi laifi han mi rara eyiyi fihan pe irọ patapata ni ọrọ Ọgbẹni Akindele Ojo Ni ọjọ karun osu kini ọdun yi 5/1/55 awọn alakoso ibi isẹ yi fun mi lasẹ lati kọwe si Akindele Ojo pe ko fi ara mọ asẹ ti wọn pa fun pe ki o ma fi iwe han mi ki o to tẹ jade o gba iwe na ko si tẹle rara, atun kọ omiran ni ọjọ kẹtala 13:1:55 lori ọrọ kanna sibẹsibẹ Akindele Ojo ko bikita

Isẹ temi gẹgẹ bi Alabojuto ni lati ma gba awọn iwe ti ẹnikẹni ba muwa si office mi fun ati jade ninu iwe, timo ba si ti ga irufẹ iwe bẹ emi yio ko tun Akindele Ojo lati ṛpe ojade, bayi ni Ọgbẹni D Ariyọ se kọ awọn iwe rẹ wa fun mi mo siko fun A Ojo osi tẹ apakan jade nigbati o di ọsẹ keji osọ fun mi pe apa keji kole jade on papa si sọ fun Ariyọ pe iwe na ko le jade fun on bayi ni A. Ojo kọ tiko gbe iwe Ariyọ toku jade tobẹ ti Ariyọ fi gba eyiti oku pada. Lẹhin gbogbo nkan ti ose yi lowa nse awawi pe on kise Olotu. Irọ patapata ni ọrọ na. Ko si otitọ kan nibẹ.



KANSẸLỌ S B. FARODOYE
On na jẹ okan ninu awọn Osẹlo pataki ti o lọ pade Ọlọla Awolọwọ ni ọjọ ti o wa bẹ Ilesa wo ni ọjọ kẹtadinlogbọn osu ti o kọja o si bẹ awọn ibi isẹ pataki wo.



ỌGBẸNI D. A. ADERỌGBA
On na wa pẹlu awọn enia pataki ti o wa sibi isin irante ti a se fun Ologbe Alufa S. O Mafẹ laipẹ yi.



ỌGBẸNI D L ADEJUYI
On jẹ ọkan ninu awọn Alakoso ibi isẹ Itẹwe ti Ijẹsa on ti gba isimi wa sile laipẹ yi, sugbọn oti pada senu isẹ rẹ ni Oke Ọya ni ọjọ kejidinlọgbọn osu to kọja.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE [illegible].

